# IPE MOSE NIBI TI ÌGBẸ́ GBÉ N JÓ

## ẸKSODU 3:1-22

## ẸKỌ 48 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ọ̀pọlọpọ li a pè, ṣugbọn diẹ li a yàn" (Matteu 22:14).**

### Mose pẹlu Awọn Agutan

Nigba ti Mose sá kuro lọdọ Farao, o joko ni Midiani, nibi ti o wà fun ogoji ọdun. A ranti pe awọn oniṣowo ara Midiani ni o mu Josẹfu lọ si Egipti. Awọn iran awọn ara Midiani wà ninu awọn Arabu lonii. Mose fẹ ọmọbinrin Jetro, alufaa Midiani kan, o si daju pe wọn jolóòtọ ninu ẹsin wọn, nitori Jetro tọ Mose wá ninu aginju lẹyin ti awọn Ọmọ Israẹli ti fi Egipti silẹ, o si fi ibukun fun Ọlọrun nitori idasilẹ nla yii. Oun paapaa rubọ si Oluwa, Mose ati Aarọni si ni ipa ati ipin ninu ẹbọ naa.

Mose ti rò pe Oluwa fẹ ki oun ran awọn eniyan oun lọwọ, awọn Ọmọ Israẹli, ṣugbọn nigba ti o gbiyanju lati ṣe ilaja laaarin awọn meji ninu wọn, wọn kọ lati gbọ́ ti rẹ̀. O gbagbọ́ pe wọn ki yoo ni ohun kan i ṣe pẹlu oun, nitori naa kò bikita lati pada si ilẹ Egipti.

Igbesi-aye ti Mose n gbé nihin yatọ patapata si eyi ti o ti gbe ni Egipti. Nibẹ o ti gbe ni ààfin ọba, o ti ni awọn iranṣẹ ti wọn n sin in, o si ti gbadun gbogbo faaji ti o wà ninu agbala ọba. Nisisiyii o n ṣọ́ agbo ẹran baba iyawo rẹ̀ ninu papa, o n ṣe iṣẹ ti o rẹlẹ̀. Ṣugbọn Ọlọrun ni ipinnu kan ninu gbogbo rẹ̀, O si n tọ́ Mose fun iṣẹ nla kan.

### Oke Ọlọrun

Ni ọjọ kan, Mose da awọn agbo ẹran yii lọ si agbegbe Oke Horebu, eyi ti a tún maa n pè ni Oke Sinai. Iwe Mimọ́ pe e ni oke Ọlọrun, a o si tun kọ́ ẹ̀kọ́ nipa awọn igba miiran ti O fi ara Rẹ̀ hàn fun awọn eniyan lori oke yii. Nihin ni Ọlọrun fun awọn Ọmọ Israẹli ni Ofin, ti O si kọ ọ sinu walaa okuta. A kọ akọsilẹ pe lori oke yii ni Ọlọrun ba Mose sọrọ "li ojukoju, bi enia ti ibá ọrẹ rẹ̀ sọ̀rọ" (Ẹksodu 33:11). Ọrọ ti Ọlọrun ba Mose sọ lati inu igbẹ́ ti n jó ni ekinni ninu ọpọlọpọ ifarahàn Ọlọrun fun Mose ni igbesi-aye rẹ.

### Ìpè

O le jẹ pe oorun mú pupọ ninu pápá naa, iná kó si le ṣe ohun ajeji fun wọn. Nitori igbẹ n jó kò ya Mose lẹnu rárá; ṣugbọn nigba ti koriko gbigbẹ yii bẹrẹ si jó ti kò si run, eyi rú Mose loju, o si lọ lati wo ohun ti o ṣe ti kò fi jona. Ọlọrun n wo ohun ti Mose yoo ṣe; nigba ti O si ri i pe o n lọ si ibi igbẹ naa, O pe e.

Ọlọrun ti mu ki imọlẹ Ihinrere tàn jade, ki gbogbo eniyan le ri i, ṣugbọn awọn eniyan diẹ ni wọn ni ifẹ lati duro wo ohun ti o n mu imọlẹ naa wa. Bi o tilẹ jẹ pe imọlẹ ẹsin-Igbagbọ́ maa n wá ṣaaju ọlaju, ti ọkẹ aimoye eniyan si n gbadun ibukun ti o mú wá si orilẹ-ede yii, ki i ṣe ọpọ eniyan ni wọn n fẹ fi ogo naa fun Ọlọrun, nipa didahun ipe Rẹ̀ ki wọn si maa gbe igbesi-aye wọn fun Un.

Nigba ti Ọlọrun ri pe Mose ṣe akiyesi iṣẹ-iyanu ti igbẹ́ ti n jó yii, O pè e, "Mose, Mose." Mose yara dahun ipe Ọlọrun kánkán. "Emi niyi." Bawo ni inu Jesu yoo ti dun to nigba ti awọn eniyan ba dahun ipe Rẹ̀ bayii pe, "Emi ni yii, mo de lati ṣe ifẹ Rẹ̀!" Awọn wọnyii ni ọkunrin, obinrin, ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin ti Ọlọrun le lò.

Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o bọ́ salubata ẹsẹ̀ rẹ̀ nitori ilẹ ibi ti o duro si nì, ilẹ mimọ́ ni. Fun akoko naa gan an o ti di ile Ọlọrun, nitori Ọlọrun n bá eniyan ní ipade nibẹ, O si fẹ ki Mose bọwọ fun un. Ki i ṣe ohun ti o pọ ju bi a ba tẹnu mọ ọn bi o ti ṣe pataki to lati bọwọ fun ile Ọlọrun. Ibikibi ti awọn eniyan ba ti pejọ pọ lati sin Ọlọrun ni ẹmi ati ni otitọ, ile Ọlọrun ni. Nigba ti Jakọbu gbọ́ ohùn Ọlọrun ti o ba a sọrọ ni Bẹtẹli, nibi ti o ti lá alá nipa awọn angẹli ti wọn n goke ti wọn si n sọkalẹ ni agbedemeji Ọrun on ayé, o gbe pẹpẹ kan kalẹ nibẹ ninu pápá, o si pe e ni ile Ọlọrun. A gbọdọ ranti pe Ọlọrun n ri ohun gbogbo ti a n ṣe; nigba ti a bá si wá siwaju Rẹ̀, a gbọdọ wà ni idakẹjẹ pẹlu irẹlẹ̀, ki a wọ aṣọ ti inu Rẹ̀ yoo dun sí, ati pẹlu ẹmi adura ninu ọkàn wa. A ni lati pa gbogbo ero nipa igbesi-aye wa tì si apa kan, ki a si sin Ọlọrun ninu ẹwà iwa-mimọ́.

### A Ṣe Ileri Idasilẹ

Ọlọrun sọ fun Mose pe Oun ni Ọlọrun Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu, awọn ẹni ti i ṣe baba nla Mose. Ọlọrun kò gbagbe awọn ileri ti O ti ṣe pe lati inu irú ọmọ wọn ni a o ti bukun fun gbogbo orilẹ-ede aye. Oun ti ṣeleri pẹlu pe, wọn yoo jogun ilẹ Kenaani. Nigba naa o dabi ẹni pe kò le ri bẹẹ nitori pe ẹrú lasan ni awọn Ọmọ Israẹli jẹ fun awọn ara Egipti, ti wọn si n ṣiṣẹ labẹ awọn akoni-ṣiṣẹ onroro.

Ṣugbọn Ọlọrun fi ye Mose pe Oun ti ri gbogbo ipọnju wọn, Oun si ti gbọ́ igbe wọn, akoko n bọ nigba ti Oun yoo da wọn silẹ, ti Oun yoo si fun wọn ni ogún ti Oun ti ṣeleri. Inu Mose yoo dun pupọ lati mọ̀ pe a o dá awọn eniyan rẹ silẹ ni tootọ́, wọn kò si ni jiya mọ́.

**Irẹra-ẹni-silẹ̀ Niwaju Ọlọrun**

Ṣugbọn nigba ti Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o ṣe aṣaaju lati mú awọn ọmọ Heberu jade kuro ninu oko-ẹrú, o kigbe pe: “Tali emi, ti emi o fi tọ̀ Farao lọ, ati ti emi o fi le mú awọn Ọmọ Israẹli jade lati Egipti wá?” Oun ki i ṣe oni jau-jau eniyan ti o ti jẹ́ ni nnkan bi ogoji ọdun sẹyin nigba ti o fẹ́ ran awọn eniyan rẹ̀ lọwọ nipa agbara ti rẹ. Nisisiyii a ti rẹ̀ ẹ́ silẹ ki o ba le sinmi le Oluwa, Ọlọrun si wi pe, “Nitõtọ emi o wà pẹlu rẹ.” Bi Ọlọrun ba ṣe ti wa, ta ni yoo kọju ijà si wa?

Awọn onirẹlẹ ni Ọlọrun le lò fun iṣẹ Rẹ̀. Nigba ti O pe Saulu lati jẹ ọba, Saulu dahun pe, “Ara Bẹnjamini ki emi iṣe? kekere ninu ẹya Israẹli? Idile mi kò si rẹhin ninu gbogbo ẹya Bẹnjamini? ẽsi ti ṣe ti iwọ sọrọ yi si mi?” (1 Samuẹli 9:21). Ṣugbọn, nigba ti Saulu gberaga, ti o si ṣaigbọran si Ọlọrun, Samuẹli ran an leti pe Ọlọrun ti fi i jẹ ọba nigba ti o kere loju ara rẹ, ṣugbọn nigba ti o gberaga, a gba ijọba naa kuro lọwọ rẹ̀.

Nigba ti Ọlọrun pe Jeremiah lati jẹ wolii, Jeremiah wi pe, “Oluwa ỌLỌRUN! Sa wò o, emi kò mọ̀ ọrọ isọ, nitori ọmọde li emi.” Ṣugbọn Ọlọrun wi pe, “Má bẹ̀ru niwaju wọn nitori emi wà pẹlu rẹ lati gbà ọ; li OLUWA wi” (Jeremiah 1:6, 8). Jeremiah si di wolii Ọlọrun ti o ya ni lẹnu to bẹẹ gẹẹ ti a kọ iwe rẹ̀ silẹ ninu Ọrọ Mimọ́ Ọlọrun.

Ẹru ba Mose lati pada sọdọ awọn Ọmọ Israẹli nitori pe kò lero pe wọn yoo feti si oun. Ṣugbọn Ọlọrun fun un ni aṣẹ. Ọlọrun sọ fun un lati sọ fun awọn eniyan naa pe Ọlọrun Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu ni O rán an. Awọn Ju, titi di igba aye Kristi paapaa, bu ọlá fun Abrahamu baba wọn pupọ pupọ; nitori naa bi Ọlọrun Abrahamu ba n ba wọn sọrọ, wọn yoo feti silẹ.

Ọlọrun sọ fun Mose ohun gbogbo ti o ni lati sọ fun awọn eniyan naa, bẹẹ gẹgẹ ni O si maa n sọ fun gbogbo awọn alufaa Rẹ̀ tootọ́. Ẹmi Ọlọrun n kọ́ olukuluku eniyan ni ohun kan naa, a o si wà lai lewu bi a ba tẹle Ọlọrun tootọ́.

**Kikọ̀ ti Farao Kọ̀**

Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o ṣa awọn aṣaaju ẹsin ninu awọn ọmọ Heberu jọ, ki o si ba wọn lọ sọdọ Farao, ki wọn beere àyè lati lọ si aginju, ki wọn ba le rubọ si Ọlọrun. Eyi ki i ṣe Farao kan naa ti o fẹ jẹ Mose niyà nitori o pa ará Egipti kan.

Awọn ara Egipti kò sin Ọlọrun otitọ. Wọn ni oriṣa pupọ, diẹ ninu wọn ni wọn rò pe wọn n gbe inu ẹranko. Fun apẹẹrẹ, nigba ti awọn Ju ba fi ọmọ maluu rubọ, o jẹ abuku fun awọn ara Egipti, nitori wọn gbagbọ́ pe ọ̀kan ninu awọn oriṣa wọn a maa wa si aye nigba kan, a si gbe inu maluu. Nitori naa, awọn Ọmọ Israẹli ni eredi ti o dara fun lilọ wọn si aginju nibi ti awọn ara Egipti kò ni ri wọn nigba ti wọn ba n rubọ si Ọlọrun. Nigba ti a ba kọ́ ẹ̀kọ́ niwaju nipa awọn ajakalẹ-arun ti o wá sori Egipti, a oo kọ́ ẹkọ́ si i nipa awọn oriṣa ti wọn n sin.

Ọlọrun mọ̀ pe Farao ki yoo fun Mose ati awọn agbagba ni àyè ti wọn beere, ṣugbọn O sọ fun Mose pe lẹyin ti idajọ pupọ ba wa sori ilẹ naa, a oo mú awọn ọmọ Heberu jade, wọn yoo si kó pupọ ninu ọrọ̀ awọn ara Egipti ti a oo fun wọn lọ́fẹ̀ẹ́.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni iṣẹ Mose ni akoko yii?

2 Orukọ mẹta wo ni a maa n pe ori oke ibi ti Mose wà yii?

3 Ki ni idahun Mose si ipe Oluwa nibi ti igbẹ́ gbé n jó?

4 Ki ni iṣẹ nlánlà ti Oluwa pe Mose fun?

5 Njẹ Oluwa ṣeleri lati wà pẹlu rẹ̀?